# AṢAKO KAN PADA WA SI ILE

**Filemoni 1-25**

**ẸKỌ 354 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: “Bi on ti jẹ ọlọrọ̀ rí, ṣugbọn nitori nyin o di talaka” (2 Kọrinti 8:9).**

### Paulu Onde

Nitori pe Paulu n waasu nipa Jesu, a ti sọ ọ sinu tubu ni Romu, ni Itali. Ki i ṣe ọdọmọkunrin mọ́, o si jẹ́ ifẹ ọkan rẹ̀ lati wà pẹlu awọn eniyan Ọlọrun ninu awọn ijọ ti o ti dá silẹ. Yoo ti dun mọ ọ to lati tun di omnira lẹẹkan si i.

Ṣugbọn kò rẹwẹsi, nitori o gbagbọ́ pe nipa adura awọn Onigbagbọ́ a o tú oun silẹ lai pẹ. Nigba ti o wà nibẹ, o kọ awọn iwe iṣiri si awọn eniyan Ọlọrun, awọn iwe wọnyii ti o jẹ ati ọwọ Ọlọrun wá jẹ́ apakan Iwe Mimọ Ọlọrun ti a n pè ni Bibeli.

Awọn irin, ẹ̀wọ̀n ati ẹ̀ṣọ́ ile-tubu kò le de ẹmi ọmọ Ọlọrun tootọ. “Ọkàn ati ẹri-ọkàn awọn baba wa wà li ominira sibẹ, bi o tilẹ ṣe pe wọn wà ninu ide ṣẹkẹṣẹkẹ ninu ile-tubu ti o ṣokunkun.” Eniyan Ọlọrun kan ti a sọ sinu tubu sọ pe wura ni a fi bo awọn ẹwọn ti a fi de e. Onde miiran fun Oluwa wi pe awọn okuta ti a fi kọ́ ile-tubu naa dabi iyùn.

### Ẹni ti a yi lọkan pada

Bi Paulu ti joko, pẹlu kalamu lọwọ rẹ̀, ọkàn rẹ̀ ti o kun fun ifẹ nla lọ sọdọ awọn ẹlomiran. A kò mọ iye awọn eniyan ti a gbala nipasẹ iṣẹ-iranṣẹ Paulu, ṣugbọn ọ̀kan ninu ọ̀pọ eniyan ti o wá sọdọ Jesu lati ọwọ Paulu ni ọdọmọkunrin kan ti a n pè ni Onesimu. Ọdọmọkunrin yii, ẹni ti i ṣe iranṣẹ Filemoni ni ilu Kolosse, di alaini inudidun o si ti sá kuro lọdọ oluwa rẹ̀ lọ si Romu. Gẹgẹ bi ẹru ti o sá, o ṣeeṣe ki a ti fi ipa mú Onesimu lati di ọmọ-ogun Romu ti a yàn lati ṣọ́ Paulu. Ni kukuru, o ti gbọ́ ti Paulu n sọ nipa Jesu, o si ti di Onigbagbọ́.

Lọjọ oni paapaa awọn onitubu ati awọn onde maa n gbọ́ nipa Jesu nigba ti awọn oṣiṣẹ Ihinrere ba lọ si awọn ile-tubu lati sọ fun awọn ẹlomiran nipa ohun ti Ọlọrun ṣe fun wọn, ati nigba ti wọn ba n pin iwe-itankalẹ Ihinrere. Ọpọlọpọ ni o ti ni idalẹbi ọkàn fun ẹ̀ṣẹ ti a si ti gbala nipasẹ iṣẹ bayii.

Nisisiyii ti Onesimu ti ri igbala o le jẹ́ oluranlọwọ fun Paulu. Inu wọn yoo ti dun to laaarin awọn wakati wọnni ti wọn jọ lò pọ̀ ninu idapọ ti Onigbagbọ́! Adura ati kikọ orin iyin wọn si Ọlọrun yoo ti pọ̀ tó!

### Pipada lọ si ọdọ oluwa rẹ̀

Ṣugbọn Paulu kò huwa anikanjọpọn ki o si dá Onesimu duro sọdọ ara rẹ̀ nibẹ. O gbọdọ rán an pada lọ sọdọ Filemoni oluwa rẹ̀. Yoo ha tẹwọ gba Onesimu bi? Yoo ha gba a pada si ipo rẹ̀ gẹgẹ bi iranṣẹ? tabi yoo ṣe alaiyọ́nu si i nitori sisalọ ti o ti salọ. Ki i ṣe pe Onesimu huwa lodi si orukọ rẹ̀ nikan itumọ eyi ti i ṣe “li èrè,” ṣugbọn o ti ṣẹ oluwa rẹ̀ pẹlu. Paulu yoo kọ iwe si Filemoni yoo si fi rán Onesimu; nigba naa ohun gbogbo yoo bọ̀ si titọ́.

### Iwe Paulu

Episteli ti Paulu si Filemoni, tabi Iwe Filemoni, jẹ iwe ti Paulu kọ ti o si bẹbẹ pe ki Filemoni gba Onesimu pada si ibi iṣẹ rẹ̀ lẹẹkan si i. Paulu mọ pe ifẹ nla ti Filemoni ni ninu ọkàn rẹ̀ yoo jẹ ki o le dariji iranṣẹ yii ti o ti huwa aiṣootọ lẹẹkan ri. Yoo si tẹwọ gba Onesimu, ki i ṣe gẹgẹ bi iranṣẹ lati maa bá iṣẹ rẹ̀ lọ nikan, ṣugbọn yoo gba a gẹgẹ bi arakunrin ninu Kristi ati gẹgẹ bi oṣiṣẹ rere fun Oluwa pẹlu.

### Atunṣe

Onesimu n fẹ lati mu ohun gbogbo ti o wọ́ ti o ti ṣe si oluwa rẹ̀ bọ̀ si titọ́. Olukuluku ẹlẹṣẹ ti o ba ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o si ri idariji gbà n fẹ lati mu awọn ohun ti o wọ́ bọ̀ si titọ. Bi o tilẹ jẹ pe ó lè ma jẹ́ ohun ti o rọrun lati ṣe, sibẹ yoo tọ awọn ti o ti ṣe aidara si lọ yoo si beere fun idariji; yoo san awọn owo ti o ti ji pada tabi eyi ti o ti fi ọ̀na eru gbà; yoo jẹwọ awọn irọ́ ti o ti pa, yoo si mu ohun gbogbo ti o wà ni ipa rẹ̀ bọ̀ si titọ́. “Bi enia buburu ba mu ògo padà, ti o si san ohun ti o ti ji padà, ti o si nrin ni ilana ìye, li aiṣe aiṣedẽde; yiyè ni yio yè, on ki o kú” (Esekiẹli 33:15).

Onesimu kò ṣe atunṣe laisi iranwọ, bakan naa ni iwọ tabi emi kò le ṣe atunṣe laisi iranwọ. Paulu bá Onesimu ṣipẹ̀, Kristi yoo jẹ́ oludamọran lọjọ oni fun olukuluku ti o ni atunṣe lati ṣe (Isaiah 9:6). Bi a ba beere pe ki O tọ́ wa ati ki O ṣamọna wa, Oun yoo ràn wá lọwọ lati mọ ọ̀na ti o dara julọ lati ṣe atunṣe wa, ati pe Oun yoo ran ẹni ti a ti ṣẹ̀ lọwọ lati ni oye ohun ti a n sọ ati lati dariji.

**Ere inu-rere**

Nigba miiran a maa n huwa rere tabi ki a ṣoore fun eniyan nitori ti ẹlomiran. A kà ninu Bibeli nipa ọmọkunrin kekere kan ti o yarọ lati igba ti o jẹ ọmọ ọdún marun-un pere. Jonatani, ẹni ti i ṣe baba ọmọkunrin yii ti jẹ́ ọ̀rẹ́ kori-kosun Dafidi. Lotitọ, Dafidi ati Jonatani fẹran ara wọn lọpọlọpọ. Nigba ti Dafidi jọba, o ranṣẹ si ọmọkunrin arọ yii o si wi fun un pe ki o máṣe bẹ̀ru. O ni oun yoo ṣoore fun un nitori ti Jonatani baba rẹ̀, ati pe oun yoo fun un ni ọ̀pọọrọ̀, ati pe ni gbogbo ọjọ-aye rẹ̀ yoo ma jẹun lori tabili ọba. Dafidi kò gbagbe iṣẹ-oore Jonatani si i, anfaani si ṣi silẹ fun un nisisiyii lati ṣe oore fun Mefiboṣeti, arọ (Ka 2 Samuẹli 4:4; 9:5-7).

**Nitori ti Ẹlomiran**

Paulu fi gbolohùn ọ̀rọ kan kun iwe rẹ̀ si ọrẹ rẹ̀ pe ki o tẹwọ gba Onesimu gẹgẹ bi o ti le tẹwọ gba Paulu: njẹ Onesimu jẹ oluwa rẹ̀ ni igbese ohun kan bi? O ha ti ṣẹ Filemoni bi? Bi o ba ri bẹẹ, Paulu wi pe "Kà a si mi lọrun." "Emi ó san a pada."

Nigba ti ọmọde ba tọ Ọlọrun wa, ti o si yi pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o si bẹbẹ fun idariji ẹ̀ṣẹ rẹ̀, Jesu yoo gba ẹjọ rẹ̀ rò, yoo si wi pe, "Baba, gba a gẹgẹ bi emi tikarami. Emi ta Ẹjẹ mi silẹ, mo si kú ki a ba le dari ji i." Ẹlẹṣẹ yii ti ṣẹ̀ si Ọlọrun, ṣugbọn nigba ti o bá wá pẹlu ironupiwada, Ọlọrun yoo dariji nitori ti Jesu.

**Pada bọ̀ Sile**

Irin ọna jijin pada si Kolosse dopin nigba ti Onesimu pada sọdọ Filemoni. Onesimu dabi ọmọ oninakuna ẹni ti o pada pẹlu aarẹ̀ ati ẹsẹ̀ riro, aṣọ yiya, owo ti tán lapo, ṣugbọn baba oninuure ti o ti ri i lati okere fi tayọtayọ dari gbogbo rẹ ji i.

Onesimu mú iwe ti Paulu kọ lati fi ba a bẹbẹ fun aanu ati idariji lọwọ. Awa ti a ti ri igbala lọjọ-oni le bojuwo ẹyin wo ọjọ ti a yi pada sọdọ Ọlọrun, pẹlu iwe idariji ti a fi Ẹjẹ Jesu iyebiye saami si lọwọ wa. "O si rù ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ; o si nṣipẹ̀ fun awọn alarekọja" (Isaiah 53:12).

**Ri Idariji**

Inu Onesimu ti dùn tó nisisiyii! Ọpẹ rẹ̀ si Paulu ẹni ti o ba a ṣipẹ̀ fun Filemoni ọga rẹ̀ yoo ti pọ̀ tó! Igbese ọpẹ ati ifẹ rẹ̀ si Paulu ati Filemoni ti pọ̀ tó! Bawo ni igbese rẹ̀ si Jesu yoo ti pọ̀ tó fun ọkàn mimọ́, akọsilẹ ti o mọ́ gaara, ati ibẹ̀rẹ igbesi-ayé titun! Igbese wa si Ọlọrun ati si Kristi, Ẹni ti o san gbese wa, ti O ru ẹ̀ru ẹ̀ṣẹ wa, ti O si sọ wa di ẹbi Ọlọrun ti pọ̀ tó? "Njẹ nitorina ẹnyin ki iṣe alejò ati atipo mọ́, ṣugbọn àjumọ jẹ ọlọ̀tọ pẹlu awọn enia mimọ́, ati awọn ará ile Ọlọrun" (Efesu 2:19).

**"Jesu san gbogbo,**
**'Gbese ti mo jẹ;**
**Ẹṣẹ ti m'abawọn wa,**
**O fọ mi fun bi sno."**

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni Paulu wà nigba ti o kọ iwe yii?
2. Ta ni a kọ ọ́ si? Ta ni a si fi rán?
3. Aayè wo ni Onesimu wà lọdọ Filemoni?
4. Nibo ni yoo jẹ́ ibujoko rẹ̀ titun?
5. Ki ni Bibeli kọ́ ni nipa atunṣe?
6. Ki ni Paulu sọ ninu iwe rẹ̀ ti o jẹ ki a mọ̀ pe oun ni ireti pe a o tú oun silẹ kuro ninu tubu?
7. Ki ni Paulu sọ nipa igbese Onesimu?
8. Ta ni Onesimu jẹ ni gbese ọpẹ nla?
9. Ta ni a jẹ ni gbese ifẹ ati isin atọkàn wá?
10. Bawo ni a ṣe le fi ifẹ wa si Jesu hàn?